# Àwọn Ànfààní Pàtàkì SUN Bucks láti mọ`

VIRGINIA DEPARTMENT OF SOCIAL SERVICES

VIRGINIA SUN BUCKS

## Virginia SUN Bucks ń pèsè ànfààní oúnjẹ iye $120 fún àwọn ọmọ tó yẹ. Ohun tí o yẹ kí o fi sọ´kàn nìyí:

- A ó fún àwọn ọmọdé tí ó ní àmúyẹ ní àwọn àn`fààní **bẹ̀rẹ̀ láti Oṣù Kẹfà Ọdún 2026 láti ìgbà dé ìgbà.** Àwọn ìdílé tí wọn ti ní EBT káàdì tẹ́lẹ̀ yóò gba àwọn **àn`fààní** náà lórí káàdì wọn tí wọ́n ní lọ́wọ́lọ́wọ́. Gbogbo àwọn ìdílé yòókù tí ó ní àmúyẹ ni a ọ́ fi Virginia SUN Bucks káàdì ránṣẹ́ sí nípa lílo àdírẹ́ẹ̀sì orí fáìlì pẹ̀lú ilé-ìwé ọmọ wọn. Ní kété tí káàdì Virginia SUN Bucks rẹ bá ti dé, tẹ̀lé àwọn ìtọ́ni tí a fi sínú rẹ̀ láti múu ṣiṣẹ́.
- **A ó tẹ iye tó sẹ́kù nínú káàdì rẹ jáde sórí ìwé ẹ̀rí ìrajà lẹ́yìn ìlò kọ̀ọ̀kan.** Lọ́nà mìíràn, o le yẹ iye tó sẹ́kù wò nípa kíkànsí gbọ́ngàn ìpè Virginia SUN Bucks lásìkò wákàtí iṣẹ́ ní **866-513-1414 (ìpè-ọ̀fẹ́).**
- Tí o bá pàdánù káàdì, kàn sí ConnectEBT ẹ̀ka oníbàárà ní **866-281-2448** láti fagilé káàdì tí ó sọnù náà kí o sì béèrè àrọ́pò.
- A lè lo àwọn ànfààní láti **ra oúnjẹ bí àwọn èso, ẹ̀fọ́ àti ẹran** ní àwọn ilé ìtàjà oúnjẹ àti àwọn ibòmíràn tí wọ́n ń gba àwọn àn`fààní SNAP EBT.

O le rí ìwífún àti àlàyé síwájú síi nípa Virginia SUN Bucks ní

**VirginiaSunBucks.com**

